28 JAN 1966


# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,588 FRIDAY DECEMBER 17, 1695 (2D)


## Awọn Ọlọpa Ri Oku Ọkan Ninu Ọlọpa To Sonu

IRO-OWODE:- Ni ọsar ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni irohin de ile iṣẹ wa pe awọn ọlọpa ọtẹlẹmuyẹ ti wọn ko lọ si ilu Iro l'eba Owode lati Eko ati Ibadan ti ri oku ọkan ninu awọn ọlọpa ti Ijọba ibilẹ meje ti irohin kọkọ fi ye wa pe o sọnu ninu ọsẹ yi, orukọ ọlọpa Ijọba ibilẹ ti awọn ọlọpa ti ri oku rẹ gbe na ni Mufutau Shobayọ ati pe ni alẹ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni awọn ọlọpa ri oku rẹ gbe.

Ninu irohin ti a ri gbọ lati ẹnu awọn ọlọpa ọtẹlẹmuyẹ ti nwọn ko lọ si ilu na lati Eko ati Ibadan fi ye wa pe ni eti bebe odo ogun ni nwọn ti ri oku Ọgbẹni Mufutau Shobayọ ti o ti ku.

Irohin na tun fi ye wa pe ọpọlọpọ awọn apa ọgbẹ ibiti nwọn ti sa lada ni o si kun gbogbo ara ọlọpa Ijọba ibilẹ ti awọn ọtẹlẹmuyẹ ri oku rẹ gbe ni eti bebe odo ogun ni eba ilu Iro.

Ọgbẹni Mufutau Shobayọ wọ inu iṣẹ ọlọpa ti Ijọba ibilẹ ninu ọdun 1959 eyiti irohin rẹ jade ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi pe o pẹlu awọn ọlọpa ti o sọnu ni ilu Iro lẹba Owode nigbati rogbodiyan kan b. silẹ ni ilu na.

Irohin fi ye wa pe Ọgbẹni Mufutau Shobayọ ni iyawo kan o si tun bi ọmọ mẹta pẹlu awọn obi rẹ ti nwọn ti di arugbo ti o fi silẹ lọ. A gbọ wipe awọn ọlọpa ti gbe oku Ọgbẹni Mufutau Shobayọ lọ si ile iwosan lakulaku ti ilu Abẹokuta lati lọ ṣe ayẹwo rẹ.

DIRẸBA

Ninu irohin to tun kan wa lọwọ ni a ti gbọ wipe awọn aja ọtẹlẹmuyẹ mẹrin ni nwọn ti ko lọ si ilu Abẹokuta

WO OJU EWE KẸFA

# OGBẸNI ESUA FI AYE RẸ SILẸ !

EKO:- Gudugbẹ ja, Ọrọ ba ẹhin yọ, agba iyanu nla ni Irohin ti o kan gbogbo enia kuu ni kutukutu owurọ ana ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi nigbati awọn enia na gbele gburo wipe, Ọgbẹni Ẹyọ E. Esua, ẹniti iṣe Alaga Igbimọ amojuto eto ibo fun Apapọ Ijọba Naijiria ti binu fi aye iṣẹ rẹ silẹ, o si ti kowe si Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe, Olori Apapọ Ijọba Naijiria wipe on ti fi aye iṣẹ na silẹ patapata lati oni yi lọ.

Ṣugbọn nigbati Ọgbẹni Esua mu lẹta rẹ na de ile Dọkita Azikiwe, o fi iwe na le Dọkita Nwafor Orizu lọwọ nitoripe Ọlọla Azikiwe ko si nile, Dokita Orizu yi lo si nṣe Adele de ninu ile rẹ titi Ọlọla Azikiwe yio fi de lati ibiti o lọ.

Lẹsẹkẹsẹ ti Irohin ifiṣẹ silẹ na ti de si ile iṣẹ wa ni kutukutu owurọ ana ni oniwe Irohin wa Ejongboro ti sare lọ si ile iṣẹ Ọgbẹni Ẹyọ Esua lati lọ fi oju kan an ati lati bere awọn gbolohun ọrọ meji kan lọwọ rẹ lori gbomisi-omi-o-to eyiti o fi silẹ lati bi ọjọ mẹta larin on ati awọn akọwe rẹ lori bi nkan ti ṣe nlọ si ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria nisisiyi.

Ṣugbọn nigbati oniwe Irohin wa de ile iṣẹ na, Ọgbẹni Esua sọ fun Ejongboro wipe, ki o maa lọ si ile-iṣẹ rẹ, sugbọn ki o maa reti kẹtẹkẹtẹ ọrọ - kan ti on yio tu silẹ nipa ibo ti awọn enia di koja lọ ni Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria ni aipe yi nitori eyiti o jẹki on fi aye iṣẹ on na silẹ.

Ni ipari, Ọgbẹni Esua sọ wipe, on mọ wipe gbogbo aiye ni nwọn yio maa reti lati gbọ ọrọ lẹnu on ni asiko yi papajulọ nipa ọrọ ibo Iwọ Orun,

O wa ṣe ileri wipe gbogbo awọn nkan ti o ṣẹlẹ ni Iwọ Orun nigba ibo na ni on yio tun sọ jade fun gbogbo awọn araiye gbọ, ti nwọn yio si mọ otitọ ọrọ nigbati asiko na to nitoripe on mọ wipe awọn enia na fẹ lati mọ bi nkan na ti ri, nitoripe awọn ti nwọn ko dibo fun ni nwọn wọle ninu ibo na.



Ogbẹni E. Eyo Esua

Ọgbẹni Esua tun sọ fun Ejongboro wipe nigbati on mu lẹta ti on fi fi aye on silẹ na lọ fun Ọlọla Nwafor Orizu, Adele Olori Apapọ Ijọba Naijiria ni owurọ yi, o ni, Dọkita Orizu sọ fun on wipe on yio maa ro ọrọ lẹta na wo na. Ṣugbọn on yio si gba a sọwọ na ti on yio fi mọ on ti Ijọba yio ba ṣe lori ọrọ na laipẹyi.

Oniwe Irohin wa kan ran wa leti wipe, ni ọjọ kini oṣu karun ọdun ti o koja lọ yi, 1961 ni nwọn yan Ọgbẹni Ẹyọ lati gba ipo ẹniti o ti wa ni aye na tẹlẹ ri Oloye Kufo Abayọmi.

Gẹgẹbi aye rẹ, Ọgbẹni Ẹyo Esua yi, kanna ni Alaga eto Igbimọ ibo fun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Lẹ u igbati Ọgbẹni Esua de aye rẹ yi, o ti di ibo meji ti awọn enia Naijiria yio di nigbana, 'gba mejeji na ni o si ni awuyewuye ninu, k si eyiti ko si ipe awọn enia ota araw n ni oko ọrọ ninu awọn ibo mejeji na ti nwọn di lati igbana ti o ti bọ si aye rẹ na:

Titi ti o si fi fi aye na silẹ ni owurọ ana yi, ni nwọn si tun nsọ ọrọ rẹ ti awọn ohunti o ṣe inu awọn ibo mejeji ti nwọn di na.

Nigbati Ọgbẹni Ẹyọ ti wa ni aye rẹ yi, o ti di igba meji ti nwọn yio dibo. Ibo kini ni ibo ti nwọn di ninu ọdun 1964 eyiti o da awuyewuye silẹ larin awọn ara ilu ti o si tun fẹrẹ da ogun silẹ nigbanna.

Nigbati nwọn di ibo ninu ọdun 1964, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA ti nwọn fẹ dibo na ni nwọn binu kọ ibo na silẹ ki awọn to tun dibo na ni ibẹrẹ ọdun yi, nitori awọn hun kan ti awọn enia na pe ni madaru ti nwọn sọ wipe o wa ni awọn adugbo kan siwaju asiko ibo na ti Ọgbẹni Esua na si sọ wipe nitootọ ni.

Bakanna ni igbati nwọn tun dibo Iwọ Orun ninu ọdun yi awọn enia tun sọ wipe, madaru wa ninu ibo na, ṣugbọn nigbati nwọn t di ibo na a ti o si di ọjọ karun lọgbọn ni Ọgbẹni Esua na sọ pe nitootọ ni madaru wa ninu ibo n, ati wipe ọ a ti awọ ti nwọn wa ni aye ak so Ijọba gba ngbana ko dara to rara.

O tun sọ ngbana wipe, awọn akowe ibo kan ṣa kuro larin ilu nigbati o yẹ lati gba iwe lọwọ awọn Aṣoju ti nwọn fẹ dibo fun nigbana, nwọn ko si gba iwe ibo lọwọ wọn.

O tun sọ pelu ninu ọrọ rẹ wipe nigbati awọn enia dibo tan, ti nwọn si ka ibo na nwọn ko sọ ninu ẹrọ Redio nigbana nwọn si mu rohin na lọ si

WO OJU EWE KẸFA

# OHUNTI IṢE IṢE ENIA YI-KA GBOGBO AIYE (Apa 2)

Ninu iwe t Ọgbẹni Lenin kọ yi ni gbogbo awọn enia na nlọ ninu iwa pẹlẹ ati iwa suuru ati iwa ipamọra ninu ohun gbogbo lati gbogbo awọn enia jakejado gbogbo agbala aiye ti nwọn si ri wipe, gbogbo ohunti awọn nṣe ni o yọrisi rere ti awọn ba ti ṣe le tẹle eto inu iwe na gẹgẹbi o ti ṣe ṣe alaye rẹ sibẹ fun wọn lati mua ṣe

## IPAMỌRA

Ete ti o wa ninu iwe yi ni awọn enia inu ilu Rọsia tẹle nigbati nwọn fi nṣe ipade kan eviti nwon ṣe ninu ọdun 1957 ati ip de ti wọn tun ṣe ninu ọdun 1960 ninu ilu Moscow, ti nwọn si tun ṣe gbogbo awọn eto inu iwe na Kinni kinni ni ọkọọkan

Aṣẹhinwa aṣẹhinbọ nigba ti nwọn ṣe gbogbo ipade wọn ninu ọdun na ni eto ofin ilana wọnyi awọn enia na ri wipe lati le ni ifẹ larin gbogbo awon enia orilẹ ede awọn gbọdọ tẹle awọn ete ti o wa ninu iwe iyebi ye na

Iwe na ṣe ọpọlọpọ alaye bi awọn enia ti ṣe le maa gbe papọ yika gbogbo ori le ede aiye ni alafia Pẹlu ifẹ larin gbogbo enia ti ija ati edeaiyede ko fi ni le ṣe lẹ larin gbogbo wọn

Lẹhin gbogbo ohunti awọn tenia, a ni gbogbo awon Aṣoju ti awon lo si ipade ọjọ na ti se gbogbo awon ohunti nwon fẹ se tan, ni nwon wa ṣeṣẹ ṣe eto ni ona ti ifẹ ati ajọsepọ re se fi le fi idi mulẹ larin gbogbo awọn enia ti nwon ngbe inu aiye

O tun ṣe atunṣe eto pẹlu bi ajọṣepọ awọn enia orilẹ ede yoku yio ti ṣe le fi idi mulẹ gẹgẹnia gbonin ju eyi ti o ti wa larin gbogbo wọn lọ ti ayọrisi rere yio si tun fi de larin gbogbo orilẹ ede aiye

Ninu ipade ti awọn Aṣoju alaṣẹ eto Ijọba ati ti awon oṣiṣẹ ṣe inu ọdun 1960 yi ninu ilu Moscow ni nwọn ti ṣe eto pẹlu wipe, o yẹ ki awọn le maa ko gbogbo awọn oṣiṣẹ ni imọ ẹ ọ ijinlẹ ati ti ọgọọn ori ki gbogbo wan le ni imọ ey ti o jinlẹ daada ti yio si wulo fun gbogbo wọn ti nwọn yio fi wulo ninu gbogbo ohun yowu ti nwọn ba nṣe ninu ile tabi ni enu iṣẹ wọn, eyiti ko ni sọ awọn oṣiṣẹ di ẹni ẹhin lẹnu iṣẹ wọn

Oro inu iwe ti Ọgbẹni Lenin ati Marx kọ ti gbogbo awọn enia na ntẹle yi on lo fun wọn ni anfani la ti le ṣe aṣeyọri gbogbo iṣẹ ti nwọn ṣe ati awọn miran ti nwọn tun nṣe lọwọ nisisiyi

Ọpọlọpọ ẹkọ nlanla ni awọn enia le ri kọ ninu iwe nla na iwe na kọ enia ni ọna ti awọn ṣe le jẹ olugbọran si awọn alaṣẹ Ijọba lẹnu ati bi awọn ti ṣe ni lati maa hu iwa rere si awọn ti nda Ijọba ba wa lọ wọ wọn ki nwọn si maa wa idagbasoke ati ilọsiwaju fun gogbo awọn ara ilu ki nwọn maṣe tun jẹ ẹniti yio ma mọ ti ara wọn nikan ti o jọ ko ni ranti awọn enia yoku nigbati nwọn ba ti de aye wọn tan.

Nipa titele gbogbo nkan ilana wọnyi ni awọn enia na ti le bori gbogbo awọn nkan ti o jẹ okẹṣoro fun wọn ninu gbogbo awọn ohunti nwọn nda owo le lati yọ ti awọn enia na ti rere iṣẹ wọn

Eto ilana iwe yi ti awon enia na ti ni l o lọwọ ṣe ọpọlọpọ anfani fun awọn enia na papajulọ ninu ipade kan ti awọn enia na Ij ṣe ni Olu ilu Czechoslovakia ti awọn ṣe ni Prague ninu ọdun 1960

Ninu ipade yi, awọn Olu ilẹ ede ti nwọn wa si lati ipade na le ni Ogoji or ṣiri ṣi awọn Aṣiwaju awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ati awọn alaṣẹ ati Alakoso eto Ijọba ni asiko na

Ninu ipade na ni awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti nwọn lọ sibẹ ti ṣe eto nipa bi ifẹ ati ajọṣepọ rere yio ṣe wa larin gbogbo awọn Orilẹ ede agbaiye patapata laisi da awọn enia Orilẹ ede kan si tabi kuro lẹhin ninu wọn.

Lati asiko yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ Asiwaju oṣelu ti ẹgbẹsi maa lepa iṣẹkan ati ajọṣepọ rere larin gbogbo awọn Orilẹ ede aiye ti nwon si nṣe eto l ti le ri wipe gbogbo awon nkan ti o ba jẹ kẹṣoro fun awon enia Orilẹ ede yoku ni awọn yio gbiyanju lati le sọ di pẹtẹlẹ fun won nipa wipe ki gbogbo won ji jo inaa mu ero okan won wa si inu ipade ajọsepo ti awon enia maa nṣe.

Ijọba Orilẹ ede ile Rọsia nsa gbogbo awon ohunti o ba ni ikapa won lati le ri wipe gbogbo nkan wa ni ipo gẹgẹbi nwọn ti ṣe wa lati ẹhin wa larin awon Orilẹ ede ti alafia ati ajọsepo rere yio fi gbilẹ larin won pẹlu ifokanbale

Ijọba na tile tun ngbiyanju lati le ri wipe ajọsẹpo rere lọ wa larin won pelu Orilẹ ede ilẹ China ati paapa larin gbogbo awon enia ti nwọn jẹ Asiwaju omo ẹgbẹ Oselu ninu awon ilu mejeji ti nwon ijo jẹ aladugbo kanna.

Lati ẹhin wa ni awọn enia Orilẹ ede ilẹ China ie ni ajọṣepọ rere ki awọn si le maa ri ẹru ara awọn ki Alafia ati ifẹ le ba wa larin awọn mejeji ni ọna ti o le fi ṣe apẹrẹ rere fun awọn enia yoku ti nwọn yio maa wo wọn fun apẹrẹ tabi bi awokọṣe ninu gbogbo awọn ohunti nwọn ba nda wọle lati ṣe.

Bi awọn enia na ba le ṣe gbogbo awọn nkan wọnyi, idagbasoke ati ilọsiwaju yio wa larin wọn, awọn yio si tun le maa yanju gbogbo awọn ohunti o ba jẹ idiwọ larin Orilẹ ede mejeji laiko jẹ wipe awọn Orilẹ ede keji yio maa gbọ larin ara awọn.

Awọn Alaṣẹ Ijọba si ti tun ṣe eto silẹ ninu nwọn yio maa ṣe ilana eto ilọsiwaju fun gbogbo awọn Oṣiṣẹ ti nwọn wa ninu ilu na lati le ni ilọsiwaju lẹnu iṣẹ won.

Ninu gbogbo awọn eto ti awọn Alaṣẹ Ijọba nṣe ninu ilu na, eto idagbasoke ni nwọn fi si ipo kini fun awọn Oṣiṣẹ ti nwọn ti nwọn wa ninu ilu na lati le ri i wipe gbogbo wọn ni nwọn wa ni aye ti o dara ti nwọn si ni itẹlọrun,

Wọ oju ewe karun


BERE FUN OJULOWO ADI—ELEGBO

## 'Congreve's Iodo Form—Ointment'



Atamatase ni egbogi "ADI-ELEGBO" yi i fun itọju gbo gbo oriṣiriṣi "EGBO—ESẸ" ni kiakia bi o ti wun ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni egbọ nipa wipe awa ko idọti ni bi ẹr gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara. Lẹhinna oju egbo ti o ba jin si u yio jeki oju re wa soke, yio si pọn daradara fun bakaru ko si mọ werewere ni yio si san patapata. Alafia de si ọ niyen:

Ri daju gbangba wipe awon sọbu ti a da oruko won si isale iwe yi ni egbe ranṣe lọ ri. Bibẹko awọn Eleru tabi onijibiti ylo ta 'Adamodi' re fun o miṣe gbọ i rao.

Bere egbogi yi ni ṣobu awon :—

WATERLOO MEDICINE STORES
8 Palm Church Street Phone 22787
LAGOS Nigeria, (Ọja Itẹ Faji

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos

## Iwe si Olotu Irohin Imole

### Ilu Abẹokuta Nfẹ Papa Işire Bọọlu

OLOTU:— Inu m i yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun Ọgbọn ati oye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati Ij ba Ibile ilu Abẹokuta lati şe iranlọwọ fun awọn ọdọ ilu Abẹokuta lati şe eto gẹgẹbi awọn yio ti se kọ Papa Isire Bọọlu si ilu wa eyiti yio jẹ Iranlọwọ nipa ere Idaraya fun awọn Ọmọ ilu na.

Mo ro pe o ti to ọdun die ti a ti nkesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ati Ijọba Ibile ilu Abẹokuta lati şe iranlọwọ yi fun eyiti awọn Ijọba na kuna lati şe fun wa Papa Isire Bọọlu si je ohunti o je pataki fun awọn enia ilu Abẹokura

Inu awa ọmọ ilu na yio dun bi Ijọba Ipinle Iwo Orun ba le se ohunti a nbere yi fun wa lati le je ki ilu Abẹokuta dabi awọn ilu mi ran eyiti yio tun mu Ilọsiwaju ba ilu wa Bakanna ni a tun kesi Ijoba Ibile ilu Abeokuta lati şe Iran lọwọ yi fun wa.

Ololu e ku ise o mo dupe fun aye ti e gba mi ọkọ Ọba ko ni sa nyin lese o.

Emi ni
L. Majẹkodunmi
EKO

Gbogbo ohunti o nşẹlẹ yi to ọkẹaimọye enia to padanu ẹmi wọn ti ọpọlọpọ ile ati mọto to jona eyiti to ohunti Alakoso Apapọ Ijọba le fi şe ofin pajawiri si Ipinlẹ.

Ohunti o şẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun ninu ọdun 1962 ko to eyi ti Apapọ Ijọba to şe ofin pajawiri si Ipinle na ati pe ko si ẹniti o padanu ẹmi rẹ tabi ita ẹjẹ silẹ ni asiko na. Eleyi si fi han pe Alhaji Abubakar wa lẹhin ẹgbẹ Dẹmọ eyiti ko tọ lati gbo pe iru ohun buburu bayi jade lati ọwọ Alakoso Apapọ Ijoba orilẹ ede kan.

Emi ni
Joseph Adeboyejọ
SHO MOLU

### A Ko Fẹ Ijoba Monafiki

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye taree ninu iwe nyin to nta bi asara gbigbona lati kesi Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa lati lo ipo rẹ rere lori ohunti o nşẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun bayi eyiti ko fi eto ofin rere ati ifọkanbalẹ fun awọn olugbe Ipinlẹ na lori ọna monafiki ti Oloye Akintọla Arẹ ilu Ogbomọshẹ sọ pe on fẹ fi şe Ijọba pelu awọn ẹlẹgbẹ rẹ ti ko si eniti o dibo yan wọn si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ na.

**WANTED**

Advance Apprentice and Apprentice Printers,

Apply In Person

Irohin Imọlẹ's Office

16, Bamgbose Street,
LAGOS

**Oja rẹ ko ta, Mase gbagbe Polowo Oja rẹ sinu Iwe Irohin Imọlẹ ki ẹ si maa Ka Iwe Irohin Imọlẹ Pẹlu Lojojumo**

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO NIPA **DYAMIREN** TỌNIKI



ALE-BI-ALE Egbogi Tọ liki jamanu, tilun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ de je fun Agbara ati Ajẹbidan işẹ lara agbalagba Ọkunrin ati Obirin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi işẹ şişe ti o ko le jẹun da ra dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lọsan tabi awọn şaa ara rẹ gbogbo ki şef un daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn işẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si adọri tabi ubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lari sọ ara di otun pafapata inu rẹ a jalọ ẹran ara rẹ ti o g banjọ yio bi yabo dada tiAra rẹ yio gbe kankan ni ugba yio sao pẹlu ioq m adeu brode o iyẹn da baş

WATERLOO MEDICINE STORES
8 Palm Church Street. Phone 22787
LAGOS Nigeria, (Ọja Ita Faji

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

# GBANJO!

NOVEMBER 15th — DECEMBER 30th 1965



J. O. SHOYINKA P. O. Box 159 Mushin.

Iwe itumo Ala, Etutu Sise ise wiwo, Ojo ibi Omo, ati Ogun Ajebidan 3s6d di 1s6d

Iwe Afose Isedale Yoruba ati Psalmu Ajebidan. 3s 6d di 2s

Turari 2s 6d Pakẹti di 1/-

o le ri iwe wọnyi ra lọdọ :-
SHOYINKA ni 9, Iyalla Street, Mushin.

# Qba Aderemi Olola Ademola Wa Ninu Awon Igbimo Alaga

IBADAN:- Irohin de ile isẹ wa ni ọjọ Iṣegun tiṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi pe awon agbalagba, ọba, Ijoye, Borokinni ilu, enia Olọrun paapa awọn ti o ni ifẹ Ọmọ Yoruba lọkan ti bẹrẹsi fiaukonu fikunlukun lati wa ọna ti alafia Igbadun ati ifọkanbalẹ yio pada si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria bi ti atehinwa. nwọn fẹ pari edeaiyede to wa larin ẹgbẹ oloye Akintọla ti njẹ Demọ pelu ẹgbẹ Itesiwaju (UPGA) ti Alhaji Adegbenro ti o jẹki Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o tun jẹ asiwaju ẹgbẹ UPGA ni Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ninu awon ti o fẹ pari ija na ni Alaiyeluwa Adesọji Aderẹmi Oloye Adetokunbọ Ademọla ada jọ fun Apapọ ilẹ Naijiria, Oloye Kofo Abayọmi, Oloye Amiuu Kosọkọ, Alhaji A W. Elias, Oloye Imam Muili, olori Lemọmu ilu Ibadan ati Eni-ọwọ S. O. Odutọla ti ilu Ibadan

Gegebi ọrọ ti a gbo lati ẹnu okan ninu awon enia ti o ṣe ipade na sọ fun oniwe irohin wa pe, ibẹrẹ ipade na dara pupọ, awọn si ni ireti pe, Olọrun yio ran awọn lọwọ lori ọro na awọn gbagbo pe ija na yio pari ni irowọ rọsẹ

Irohin ipade na tun so pe nwọn ti ba awon die ninu awon asiwaju UPGA soro lori ọro nwon lati pana edeaiyede o wa ni Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria eyiti o dẹgbinrin ọtẹ bi a ti npa okan ni. Omiran tun nṣu, Alhaji Adegbenro so eto ẹgbẹ rẹ fun ipade na gegebi irohin ti a gbo.

Gegebi ọro ti okan ninu awon ti o ṣe ipade na so fun oniwe Irohin to wa ni Ibadan ni o tun ṣe alaye fun pe, bakanna ni awon ti lo ba awon asiwaju ẹgbẹ Demo soro lori oro kanna ni ojo ojo 'Bo tiṣe ojo kẹdogun oṣu yi.

A tun ti gbo label: pe awon omọ egbe Obinrin ti ilu Eko ti lo si Ibadan lati lo fi oju kan awon ogun na gbongbo omo ọmọ egbe UPGA ati ti Demo lati ona ti awon mejeji yio fi imo sọkan ti nwon yio jijo maa wa alafia awa Ọmọ Yoruba

# ★ YE IRAWO RE WO ★

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Ọjọ Ire ni oni yi yi jẹ fun ọ, ati Ire ni ohun ti o nro ninu ọkan rẹ yio jasi, ṣugbọn ki o ṣọra ki o maṣe ba ẹni kan jowu, ki o ma ba di ija ati aso.

PISCES (Feb 21 Mar 20) Ojọ oni dara lati fi iwa Irẹpọ pẹlu awọn enia, ki ẹ si da ojọ ti ẹ o jijo ba ara nyin rin Irin ajo, ṣugbọn ki ẹ maṣe jẹki adehun nyin yẹ.

ARIES (Mar 21 April 20) Maṣe lo orisi egbogi rupọ nigbakan ki o ma ba dio lọwọ lati ṣe iṣe rẹ gẹgẹbi o ti se eto rẹ silẹ ma ẹgbe ara rẹ ga ju bi o ti ye lọ

TAURUS (April 21-May 20) A san ati aigbadun yio ba ọ ja loni o yẹ ki o rin mọ alagba kan ti yio da o lara ya Idamu ọkan yio de si o ti Iwọ ko ni mọ bi aiye rẹ ti nlo si Kuku jẹ fiaji o si ode diẹ rawa boya yio san.

GEMINI (May 21 July 21) If kanbale ati idera yo wa fun ọ juburata lori Igbadun ati Idera ya yio wa fun iwọ pelu enikeji rẹ iwo o si gbo irohin aladun iwo yio si ri owo lo

CANCER (June 22-July 22) Ire ati adun po fun o loni ṣugbon o ye ki o kapa ir wẹsi nipa cidubule ki o s sun.

LEO (July 21 Aug 22) Ọjo iyaru li oni ti ko ni jeki inu dun sora ki o ma se ṣe lara ẹnikankan nitori pe ojojo yio bẹ o

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ode tabi idalẹ ti o ba lo loni yio fi ire wa ba o iwo yio ba orisirisi awon enia pa de tobẹ ti ẹnu yio ya o iṣe re yio ma ni ilosiwaju ki o si kowe si awon orẹ rẹ

LIBRA Sep 24 Oct 23:- Arẹ ara le de si ọ loni, ṣugbon ki mo wipe odo rẹ ni gbogbo aiye nfi oju si, ki o si to u alafia ara rẹ, so ehun ti Iwọ yio jẹ loni ki o si lo dubulẹ

SCORPIO Oct 24 Nov 22 Orisirisi erongba lo mbẹ lokan rẹ lo si ipade awon enia pataki ki o si ba won jiro ro ohun ti o si gbero u u kan re ire ni yio jasi

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Iwọ yio ṣe orire nitori ripe ninu awon ẹgbẹ re to dara a iwo wa oro ohun ti o nso nipe owo yio sanfani

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Arẹ yio mu o loni yio si da o lamu nitoripe iwo ko le ba awon isoro wai kujo Kuku gba fun Ọlorun laipe iwo yio si ri alafia


# Kere o Kere o! Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanuu Egbogi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni as ko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan so wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri ẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko doro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki wọn ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe enia nipa sisedi ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile meje abọ (7/-6 pere Igo kekere ṣile mẹrin abo (4/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos P. O Box 333

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba
ATI NI ṢỌBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN
NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone.- 22878 Lagos Nigeria. (Ọja Ita Faji

## IWE KOṢEMANI NI EYI
IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe YẸWO fun ara rẹ

"KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d ere ni nta

# OHUNTI IṢE IṢE ENIA YI-KA GBOGBO AIYE (Apa 2)

## Lati Oju Ewe Keji

Sugbọn bi awọn enia na ti nṣe ipae ni lowọ ni nwọn fi rdan fun gbogbo wọn enia ti nwọn wa si inu ipade na tabi gbogbo awọn Aṣoju awọn ọmọ ẹgbẹ ti nwọn le si ipade na pe bi otitọ jẹ pe awọn nle pa eto iṣokan ninu aiye si bẹ na awọn enia na nmu da gbogbo awọn enia loju pe awọn ko fi oranyan tabi dandangbon lee lori fun awọn Aṣoju Orilẹ ede pe ki nwọn ma fi oranyan g a ohunti awọn ba ṣe tabi lati ma fi ipa mu won ki nwọn to le ṣe nkan.

Ṣugbọn ki nwọn to le ṣe ohunkohun ninu ipade na, nwọn ngomu awọn ohunti awọn Aṣoju ẹgbẹ Oṣelu fẹ ki nwọn to le gba wọn ni imọran ninu awọn ohun na ni ọna ti nwọn lero pe o le dara fun wọ ni ọjọ iwaju ninu eto ati ṣe Ijọba ara ẹni eyiti nwọn ngba awọn en a na ni imọran ni ọna ti o dara lati ma ṣe.

Nwọn si tun ngmu da gbogbo awọn ti nwọn jẹ Aṣiwaju ẹgbẹ Oṣelu ti won e si ipade na pe. bi nwọn ba le gba imọran ti awọn nfun won. ti nwon si tun le tẹle apẹrẹ rere ti nwọn ngba won ni imoran ṣe won yi nwon yio ri pe Ijoba won yio le ma se iṣẹ ni ona ti yio fi ma mu inu gbogbo awon ara ilu dun.

Bakanna ni awon enia na tun nso fun gbogbo awon Asiwaju omo ẹgbẹ Oṣelu ti nwon lo si ipade ojo na pe ki iṣe pe awon enia ni lati ma so oro tabi ma ṣe ileri asan fun awọn ara ilu, ṣugbọn awon gbo do jẹ ki ise won ati iru ẹṣẹ won ma so oro ju ohunti nwon nso jade lẹnu lo fun awon ara ilu lati ma se ni nu ohun gbogbo.

Ni gbogbo igba ni awọn ti nwan ba nṣe Aṣiwaju ẹgbẹ Oṣelu ni lati ma a ba awọn oke soro pade nigba m ran lapa awọn ajẹṣepe gbogbo awọn ile ti nwọn nbẹ ninu aiye ati awọn ilẹ okere ti awọn jijọ nse aṣepo larin ara wọn.

Ṣugbọn sibẹ na, nwọn ko gbọdọ jẹki agbara da awọn ninu gbogbo wahala wọn lati ma le p a ohunti yio maa mu ajọṣepọ rere wa, ki iṣe larin awọn enia ti nwọn jẹ ara ilu ti w ọ n nikan, ṣugbọn larin gbogbo awọn enia Orilẹ e d e aiye gbogbo ni nwọn gbọdọ ma a wa awọn n k a n wọnyi pẹlu ki alafia le ba wa larin gbogbo enia ti nwọn wa yika gbogbo Orilẹ ede laiko si ogun tabi ọta larin gbogbo wọn.

Ṣugbọn bi awọn enia na ba nipa lati ma k ọ l u awọn enia Orilẹ ede Ijọba alagbara aiye ti nwọn si tun nṣe atako awọn enia Orilẹ ede na tabi awọn enia Orilẹ ede miran ninu aiye, ko ni si anfani kan ti iru awọn enia na le ri gba ninu ṣiṣe awọn nkan ilodisi bawọnyi ju wipe, ki nwọn ma a ṣe ohunti yio maa mu ifaṣẹhin wa fun wọn lọ.

Ile ipẹlu yio si tun ma aṣe ibajẹ fun dasilẹ ati ajọṣepọ rere ti o wa larin wọn ati awọn Orilẹ ede yoku eyi si le mu ipalara wa fun wọn g gẹgẹ Orilẹ ede kan si ekeji wa ti o ogun tabi ọtẹ si le ti iparẹ bẹ ilẹ la rin awọn Orilẹ ede mejeji na latro tẹlẹ.

Bi iru nkan bẹ ẹ ba si wa, eleyi yio mu sare lopọlọpọ fun gbogbo awọn ara ilu ati ti nwọn nṣe lori fun lati le ma laka ka ninu gbogbo ohunti nwọn ba nse ati awọn ohun ti nwọn nwon ba nfẹ fun ara wọn ninu ilu ki o le tete tẹ nwon lọwọ fun ilo ti ara won nigbayowu ti nwọn ba nfẹ.

Ijoba Orilẹ ede R o s i a npese, yio si tubọ tun ma pese fun gbogbo awon Orilẹ ede ti nwọn ba nfẹ iranlọwọ Ijoba ni ona kona ti nwọn ba nfẹ ti nwon ba si mo wipe yio mu itẹlọrun wa fun awon.

Nipa ṣiṣe bayi ni Ijọba na se npese gbogbo awon ohun iranlowo ti a w o n enia Orilẹ ede Ilẹ Vieta m nfẹ fun wọn nigbagbogbo ti nwọn ba ti b e r e fun iranlowo lati ọ w ọ Ijọba won.

Nipa sise ba yi, awọn enia Orilẹ ede Ilẹ Rosia rii daju pe wọn nṣe gbogbo awọn ohunti o wa ni ikawọ won lati ma fi ṣe iranlọwọ fun gbogbo awọn enia orilẹ ede aiye ki ajọṣepọ rere le ba wa larin wọn, ki iṣe ni bikansoso pẹlu ṣugbọn yika gbogbọ igun mẹrẹrin aiye ni nwon nṣe ohunti nwọn nṣe pẹlu.

Nitori idi e yi, Ọlọla ham V m Dong, Ale oso Ijoba Orilẹ ede ile Vietnam sọ ninu ọrọ rẹ ngbati Ijoba Orilẹ ede ilẹ Rosia fi nṣe Ajoyo Iranti ọdun ejidinl d ta ti nwon gba Ominira ninu ilẹ rẹ ni ba ra wipe; on dupẹ l o w o awon enia Orilẹ ede ilẹ Rosia ti nwon ni si awon enia Orilẹ ede ilẹ won.


## Ha Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ An O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si da a pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun dadara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu fun ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu leitaja kakiri Orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS

AMOS GBENLE & BROTHERS

34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West

LAGOS

